AWON OHUN PATAKI
NINU IWE OSE YI
Esi oro Gabriel Dada
Oju iwe 5
Kabo Obabirin keji
Oju iwe 5
Ebbe omo ogun Nigeria
Oju iwe 8
Esi oro Ogbeni Fapohund
Oju iwe 8

# IRAHO ★ OBOKUN

Pataki ibewo Obabirin
Oju iwe 1
Asidikini be Ijebu-jesa wo
Oju iwe 1
Ibipada si Esa-oke
Oju iwe 2
Ariyanjiyan nbutiri oro je
Oju iwe 3
Isaku Ajeji lorileda
Oju iwe 4

Vol 4 No. 171 ILESHA MONDAY JANUARY 30 1956 IYE OWO: TORO

# OBABIRIN ILE GESI, OKO ATI AWON EMEWA RE TIDE SI EKO

## ŞIŞE PATAKI IBEWO OBABIRIN.

(Lati owo Kanselo Akindele Ojo Farapo G 33, Isare)

Esisi o ba ufojojumo ka iwe Irohin gbogbo yio rişe lati nkan bi oju merin sehin ti ikede ti j a d e lati Afin Obabirin ile Gesi pe Kabiyesi na ati oko re yio be Nigeria wo ti imora-sile ti nlo bi rere jakejado Nigeria.

Nitori mimurasile de ibewo awon Kabiyesi na, nohin nfiyeni, bi a ko ba fe feju ti po owo ti gbogbo awon ijoba Nigeria yio ti gba awon alejo na yio to egberun poun lona edegbeta (about £500, 000.)

Ogonlogo awon eniti lo ti nso ke mawo na ti poju, elominran pupo ifemmofo ni. Şugbon nigba ti yio mo bi ibewo na se pataki to ti koni sore mawo na kere die

NIPA OMINIRA

Lati opolopo odun sehin ni Nigeria ti ie şokoto bo lati ma kigbe ominira tabi oro lati ma şeto ijoba tii Iqara tii labe itosona Ijoba Gesi tabi pipigo mo ti Kabiyesi Obabirin Gesi.

Lati awon eniti ede bi tiwa tiwon nkigbe lati lero bejoba tai fonra tai bi ewa yi po labe ijoba Obabirin Oba Gesi to be ge, tofi jepe laifojuri fun rare, o se nse fun awon "ohun ti a ni lo-dimi" lati me fodi oro ban Kabiyesi na pe "awon ojumila die lo kan nkigbe ominira Nieria o jare" atipe "Nigeria na papa ko ju ilu kekere kan".

Nipa be ti a ba tile nkigbe kosu si nitoripe awon to tiwa nigbe oro wa gbodi. Orile ede bi tiwa nipo labe Gesi tobe ti 'a kole sope ki Kabiyesi na ma fi ojojumo gbo tiwa.

Şugbon bine ti Oba abo lati

Ibere ni oju iwe 6

## AŞIDIKINI JADESIMI BE IJEBU-JEŞA WO

(Lati owo Awuimin bi ogona Ijebu-Jesa

Ni ojo Isimi ti se ojo kedogun osu kini odun yi ni Eni owo julo Asidikini L. O. A. Jadesimi, Ala-fa agba ni agbegbe yi ati Iyawo re wa be Ijebu-Jesa ati agbegbe re wo.

Ni ae go meji abo ni Eni owo Jadesimi se isin Ipinfunni onje ale Oluwa.

Ni agogo mewa ni isin yi bere ile Olorun kun ni akunya fun awon eniti Iso ati awon ti nwon wa lati agbegbe lati ri Eni owo yi ku abo.

Nigbati Eni owo yi bere iwasu re, ookin ko to afojuba ni, daju daju ami Olorun nba okunrin na rin.

Ni agogo kan osan ni awon asoju Ijo ati Ijebu, Iwoye Ilu Odo ati Ese pejo si gbongan ile Alufa lati ki Eni owo wa ku abo ati lati be ti eni ko ti rau, awon Ogbeni meji yi ni a yan lati 'ba a soro Ogbeni S. W. Omomuyi ati I. D. A. Wilberforce. Ninu oro won, awon fi alai agbegbe yi han Eni owo julo yi, on na si se opo ala-ye ti o te eti lorun, lehin eyi a fi onje ole to ka lehin ti a ti fi nkan die panu

Die ninu awon ti o wa nibe Rev. D. A- Yeloye) Messrs. J O Fasitagun, S W Omomuyi) B O Orioke I D A Wilberforce, O Abogan) Chief J F Oladende ati awon ti o ku ti a ko se ma ka ... 



ALAYELUWA OBABIRIN ELISABETI KEJI

Lati ojo Alamisi ni kebeyesi, Alayeluwa, Obabirin Elisabeti ti fila London sile lati wa be Nigeria wo fun ose meta. Lati ojo Jimo to koja ni ... awon emewa re ti de si Eko. Ilu Eko tikun fun ogun-logo eniti ti won fe woran dide Oba na.

## PRESS ANNOUNCEMENT

This is to inform the Secretary/Treasurers, chairmen and members of Local Councils that Printed Forms for the day-to-day use of the Local Councils had been printed for sale.



AWON EŞIN ATONA WON ATI KEKE OBABIRIN

Eyi ni aworan awon esin pelu awon atona won lasiko ti won nfa keke Obabirin ile Gesi Igbati Oba ba nlo sode eyo pataki ni ma nlo keke na. Iru keke na ni Kabiyesi na lo de idi oko ofurufu lojo Jimo to koja nigbati o abo ni Nigeria.

## KANSELO ATI IJOYE YONU NIGBIMO

Ni ojo Isinbilenojoa ose kokan la ... to koja ni igbimo ijoba akamo Ilesha se ipade. Nitori ipade na ni Kanselo Awe ti daba pe ki igbimo da fowo si pe ki awon ijoye merin ati Kanselo meje ti I wa ipade igbimo na je yiyojunu.

Ni igbehin oro re, Kanselo na se alaye kan bi awon Kanselo ati awon oloye na se ko lati wa ipade lati ojo ti won ti yan won.

O ni dajo be nse ni won akowe si Olori ijoba pe ko ba awon wipe bi awon yio tise da ijoba se lodo won.

Lehin oro gun, igbimo na fowo si, won si kowe si Alale Ijoba akopo Ijesa ati awon alase gbogbo pe awon ti yo awon Kanselo meje ati Oloye merin ti won nalwa si ipade nigba mewa lalai. Won fowo si, won si ti yo won kuro



ỌLỌLA ALAN LENNOX-BOYD.

Eyi ni Ẹni owo, Ọlọla Alan Lennox-Boyd, ẹniti o jẹ olori awọn ijọba kọlọni gbogbo. Nigbati o bẹ Nigeria wo ni ọdun to koja ni awọn jagunjagun Nigeria di adiro ọla yi fun. On na pẹlu awọn to si Ọbabinrin de ebute ọkọ ofurufu nigbati o bọ ni Nigeria.

## AGBẸ IJẸṢA GBẸBUN TO GAJU.

Lati ogunjọ oṣu yi ni ifihan agbẹ ti Ifẹ ati Ijẹṣa ti bẹrẹ

Lẹhin ti wọn ti pari ti ipinlẹ Ijẹṣa ati ti Ifẹ ni wọn ko awọn to daraju ninu ifihan ti ipinlẹ mejeji pade lojo kọkanlelogun oṣu yi.

Kabiyesi, Alaiyeluwa, Ọwa Ajimoko keji lo ṣe alaga. Ninu awọn isọgbe rẹ ni Alaiyeluwa Adenle Kini, Ataọja ti Oṣogbo.

Alaiyeluwa Ọni Ifẹ, Sir Aderẹmi Adesoji keji, K.B.E ṣi eto ifihan na.

Ninu ọrọ rẹ, o sọ wipe ni asiko kan, nigbati Ijẹṣa degbe Atunluṣe silẹ ni awọn ara Ifẹ bẹrẹ si kọ aṣa wọn.

O ni iru ipinu ohun rere bayi lo ma nmu itẹsiwaju wa larin Ijẹṣa ati Ifẹ.

Nigbati wọn ṣe ayẹwo awọn ohun ifihan iṣẹ agbẹ to daraju, wọn ripe ti ipinlẹ Ijẹṣa lo daraju. Nitoribẹ ni wọn gbe ẹbun ife (Cup) ti awọn alaṣẹ iṣẹ agbẹ fi silẹ.

Ẹniti a gbọ pe o ni ohun ti wọn fi gba ife daradara na fun ipinlẹ Ijẹṣa ni Agunlejika keji lọja Okebode lẹhin igbati on ti gba ọpọlọpọ ẹbun gẹgẹ bi ẹnikan.

## A DELABU FIPO RẸ SILẸ

ỌLỌLA Adegoke Adelabu ẹniti o jẹ ọkan ninu awọn olu ṣeto ninu ijọba akopọ tifi ipo rẹ silẹ.

Ohun to fa nipe iwadi na na eto iṣẹ ijọba ibadan da a lẹbi gẹgẹbi alaga igbimọ ijọba na.

Ọlọla na tisọ tẹlẹ o si ntẹnumọ titi pe ebi oluwadi na da on kii ṣe to on, o ni kosi otitọ ninu ẹsun ti awọn ọta ka si on lọrọ.



DIDURO AWỌN OLOGUN FUN IBỌWỌ FUN GOMINA AGBA

Eyi ni iduro ibọlafun ti awọn jagunjagun Nigeria ṣe fun Gomina Agba ti Nigeria Ọlọla Sir James Robertson lọjọ ti wọn ṣi aseye idasilẹ kotu giga ti akopọ ilẹ Nigeria. Niwaju kotu giga na ni wọn ti ya aworan yi.

## MO KI Ẹ KABỌ ỌBA ILU OYINBO

(Lati Ọwọ Woli Eleti Ọfẹ)

Kabiyesi Ọba Ilu Oyinbo ku abọ, ẹku ifẹ wa. Ki Oluwa jẹki ẹ pẹ fun wa.

Lọdun ti ẹ wa bẹ wa wo yi, ki Oluwa jẹki o jẹ ọdun ayọ fun gbogbo wa. Ki Ọlọrun jẹki aboyun bi tibi tire, ki o si ṣiṣọ anu wo awọn agan, Ki awọn koniṣẹ ri iṣẹ ṣe, ki awọn to ni iṣẹ lọwọ ma lọ siwaju si.

A dupẹ lọpọlọpọ lọwọ Oluwa wipe lakoko tiwa ni Ọba Ilu Oyinbo bẹ orilẹ ede wa wo. Iṣẹ ti Ọlọrun si ran mi si ayin ni mo wi fun yin yen.

Emi Eleti ọfẹ nlọ pade Ọba Ilu Oyinbo ni Ibadan ni ọjọ marundilogbọn oni. Gbogbo bi iroyin ohun ba ti jẹ emi yio jẹki ẹnyin ọkawe wa ti gbọ o.

Ki emi ma ba ọrọ mi ọsẹ yi lọ lai ni idaduro kan, Burọda dẹrẹba Biọdun tun fẹ gbidanwo diẹ o. Bi Biọdun dẹrẹba ba si ti ngbiyanju si ẹnyin yio ma gbọ lẹhin ọsẹ. Ṣugbọn ninu gbogbo ohun ti a nwi nile yi, mureke ni Burada tun ngbiyanju. O ele koja aye rẹ.

Lati nkan bi ọsẹ diẹ sẹhin ni ọgbẹni kan ti gbe aṣẹwo tuntun kan wa lati ilu Eko o si fi wọ si ọgba imufaji kan. Eyi ma ki ọja awọn onile ku ta, ti ajeji ti bẹrẹ si ta dada.

Nigbati awọn aṣẹwo onile pe ibẹ ti wọn fa ajeji wọn kigbe lohun rara wipe 'Iwọ aṣẹwo ilu Eko, kini ṣe tawa tirẹ, lọwọ maṣe dawa joro".

Ọsa ẹgẹ aṣẹwo onile adi aiyẹn o Nkan to fi ri bẹ ni wipe, alalẹ ni wọn ma elọic palẹ de ile imufaji ti wọn ba si ti foja kan okunrin kan to nfi "beer" gbadun ẹmin rẹ, ọrọ buṣe. Wọn a si bere ohun ti oyinbo npe ni "Indi Raid" Gbogbo nyin lẹ mọ adugbo ti Ọlọrun yio kọ parẹ ti idajọ ba de.

"Eruku-ṣẹko njẹ ẹ ti gbọ nipa ọgbẹni to gba Kọntirakitọ obirin ile igbayọ ti mo nwi yi?. Ko to fun ẹ laye lati ri obirin lwọ ni lati fun ti siile kan owo ereede (Commission) tirẹ lẹhin eyi lo wa ku ṣile marun ti oni nkan.

Lagbaja ti de ẹnin rẹ nibẹ, bẹ si ni lakasogbe na se. Ṣugbọn aa o, Burọda kan lu ayẹwo na ni jibiti, on gbawin kini yi ni, o san ṣile mẹta silẹ ninu ṣile marun, o ni ki wọn "debit" on fun iyoku. Lati ọjọ na ni sisi ti nwa lati gba balasi akanti rẹ.

"Ẹniti nsa koko, on pẹlu koko rẹ ni yio jẹ gbe."

Mo fẹ ki gbogbo aṣẹwo Ileṣa wo iwe Isaiah ori karundinlogoji ẹsẹ kejo wipe 'Opopo kan yio si wa ati ọna kan ti a o si ma pe ni "Ọna iwa mimọ" alaimọ kan bi ti awọn aṣẹwo ki yio wa nibẹ. Gbogbo ọrọ yi fi han wipe gbogbo ohun ti awọn abaluje ba nṣe ni ile aiye, iya rẹ duro de wọn sọrun.

Alafia jina si awọn agbegilodo ma bẹru epe, bẹ si ni Ọlọrun awọn ọmọ ogun wi, nitori iṣẹ ibi wọn poju. Ọlọrun fun ibakasiẹ lati wọ oju abẹrẹ ju fun aṣẹwo lati wọ ijọba Ọlọrun.

Gbogbo aṣẹwo ti o ba si mọ wipe on yako ki on bẹrẹ lati ma ṣe ibi, ṣugbọn o da mi loju wipe, ọjọ kan nbọ ti Oluwa yio pa fitila ninu okunkun biribiri.

Ẹ wa gbọ na o. ṣe Sariyu ko ni da ṣile mẹwa to gba lọwọ ọmọ Anaye pada fun ni. Ọtọ lẹni ṣe mureke, ọtọ lẹni tun nsanwo rẹ.

Kokumọ alẹja, irohin rẹ kan mi o, ṣugbọn yio to ọsẹ to mbọ ka to rira.

Ganiyu ati awọn elere rẹ ti ko awọn ẹrọ gbohungbohun de ilu Ileṣa ti wọn yio fi ma kọrin bi ti Rio Lindo. Njẹ nko sọfun yin lọsẹ to kọja wipe Ileṣa fẹrẹ da bi ilu Oyinbo. "Eruku ṣẹkẹ o."

Njẹ ti Ọlọrun ba tilẹ fọ ṣe idajọ Olowo ko ma ni ṣoju talaka? Bi Ọlọrun ba fẹ ṣe idajọ "Ayiluka" ko ni ṣe iṣoju alagbafọ. Gberaka sida, ọmọ ẹsọ.

Awọn "ọdọmọkunrin tun bẹrẹ lati ma tabuka ara wọn o, ewo ni ti awọn "Gentlemen" ti wọn nja leri bia onigia ni ile John Ọmọle. Eyi ko dara. Nkan bahun ma nba abuku ilu ni.

Ewo tun ni ti ija gbaju nọ meji ni ile igbayọ ṣe ki ṣe to ti aṣẹwo tuntun? Ina njo Mọkwa" ati "Eruku ṣẹkọ".

Iyẹn ara meji ti wọn ma nṣe nile ibiti oloku tabi oniyawo ba ti ngbe.

Igbeyawo bi rẹrẹ o "Nṣe ni mo ngburo ti wọn nkọrin

## PATAKI IBEWO OBABIRIN

(Bere lati oju iwe ekini)

wa foju ri funra re yi, bi ko tile le de gbogbo ile Nigeria. Igbati o ba kuro ni Eko, toba de Kaduna, to tun lo si Jos, to yida lati ibe o di Enugun ati Port Harcourt, to ti ibe pbera o di Eko, dajudaju, iru arinyigo yi yio fihan Oba na pe lotito ni ile Nigeria gboro ju ile Gesi lo.

Nipa be on ati ogunlogo awon ti yio ba wa yio gba pe lotito ni Nigeria lero si eto lati ma seto ijoba eni fun ara eni

Lehin igbati Kabiyesi na ba kuro ni Eko yio ba oko oju irin de Ibadan lehin igbati o ba duro die nitosi Abeokuta. Lehinna ni yio ti Ibadan wo oko ile ba Ijebu jade si Eko.

O dun ni pe aye koni si fun Kabiyesi na lati wo inu opolopo awon ilu wonyi sugbon nigbati o ba de Ibadan (ilu ti titobi re ewon ni ile Afrika), ti o ba foju ri omo ile iwe bi egbe-un lona igba laika ero iworan; dajudaju ti Obabirin na ba kuro ni Nigeria tan, ti a ba fohun kan yanlekun bere eto lati seto ijoba wa funra wa, Kabiyesi na yio mo pe lotito, orile-ede ti o to be lo nbere.

### PIPE NIGERIA HAN

Gbogbo ibi lo tije mimo pe eniti a ba mo ni a agbe ara le. Ao jiae ni o, no sowo ni o, ao ra tabi ao keko tabi ao fe ki won ma keko lodo wa ni bi, bi a ko ba je mimo si eniti a fe ba sepo asepo na koni le rorun.

Nitori eyi onakona ni awon enia pataki pataki ti ngba lati ripe Nigeria je mimo si gbogbo aiye. Onakona ni ijoba Nigeria papa ti ngba lati ripe won fi Nigeria han gbogbo agbaiye.

Ninu igbiyanju lati ripe Nigeria je mimo fun gbogbo agbaiye a ti ran ogunlogo omo wa lo si ode agbaiye lati keko, ogunlogo enia pataki pataki ti de, pupo. Oba ati Ijoye wa ti nlo irinajo lo sode agbaiye. Awon agbaboolu wa, awon elere idaraya wa, awon elere ijere wa. Gbogbo iwonyi lo tise iwon ti won le se lati fi Nigeria han.

Lati ripe agogo ifihan Nigeria nlo lati awon okawe ni ayida aiye yi, ogunlogo iwe irohin ni awon ojogbon iwe dda sile. Opolopo nlojojumo jade, opo njade losose, beni tolososu njade. Gbogbo iwonyi je igbiyanju lati fi Nigeria han.

Gbogbo owo ti a ti nna lori gbogbo awon isapa wonyi tiju egbe gberun poun lona egberun aimoye lo.

Ohun ti a fi bi egbegberun ona egberun aimoye poun se, li a si ti kosi lati bi ogota odun yi, ti ko i ti bosi toyi, o daju pe ibewo Obabirin ati oko re yio fere le se eyi to poju lo.

### ELERO OLUGBOHUN

Fun akiyesi, ninu awon enia pataki pataki to ti je mimo si ogunlogo awon ilu olaju gegebi awon to nfigbagbogbo soro ninu ero olugbohun ti ilu oyinbo (BBC) ti awon ni nipe obabirin bo wa be Nigeria wo ni awon Ogbeni Wynford Topping, Godfrey Talbort O. B. E., Andrey Russell ati Eric Lyceti.

Gbogbo awon wonyi lo je mimo si gbogbo awon orile ede to lero olugbohun gegebi eda to ti nfero olugbohun soro si agbaiye nipa ilosiwaju ati itesiwaju orile ede gbogbo.

Ti mo ba sope ki nfenu ba itan won ni enikokan yio gba aye ati asiko, sugbon gbogbo won lo ti je oluko ni opolopo ile Eko gigiga. Won se pataki tobe ge to fi jepe awon lo ma nsaba ba oba rin iru irin ajo bayi.

### ONIROHIN ODE AGBAIYE

Eyi ni awon oniwe irohin ti won je olokiki lati ibikibi lode agbaiye ti won tide si ile Nigeria nitori ibewo obabirin ati oko re. Awon na ni:-

(Bere ni oju iwe 7)



AWON ESIN TO NFA KEKE OLA FOBA

Awon esin funfun mejo lo ma nto lati fa keke ola fu Obabirin Elisabeti keji papa nigbati o lo sibi ajeye iwuye (coronation) re. Iru keke ola be ni Oba nagun de idi oko nigbati o ebo si Nigeria.



KANSELO MICHAELI FALOPE

On ni alaga igbimo akamo ijoba Ibodi. On na pelu awon enia pataki pataki to wa si bi ifihan ise agbe ti won se laipe. Opolopo agbe gba ebun nibi ifihan na fun didara ti nkan oko won dara.

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu

## "IRAWO OBOKUN"

| | | | |
|---|---|---|---|
| | OJU EWE KINI | | |
| Igba | 1—12 | 8s. | fun insi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6d. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 7s. | „ „ „ |
| | OJU EWE KEJI | | |
| Igba | 1—12 | 5s | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 4s. | „ „ „ |
| | OJU EWE KETA | | |
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. „ | „ „ |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | „ „ „ |
| | OJU EWE KEJO | | |
| Igba | 1—12 | 6s. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 5s. | „ „ „ |

OJU EWE 4, 5, 6, ATI 7 JE OWO KANNA

PELU TI, OJU EWE [illegible].

## PATAKI IBEWO ỌBABIRIN

(Berẹ lati oju iwe 6)

| IWE IROHIN | ONIROHIN | AYAWORAN |
|---|---|---|
| Daily Mail | Mulchron, Vincent | Wallace, H. A. |
| Daily Telegraph | Harvey, Frank | — |
| Daily Mirror | Walter John | |
| | Lloyd-Williams, Ann | Reid, Fred; Sidey, Arthur |
| The Times | Baughan, Francis | Barker J. |
| Daily Herald | Tyler, Patricia | — |
| Daily Express | Redfern, John | Gerelli, Ronald; Johnson, David |
| Daily Sketch | — | |
| News Chronicle | Vine, George | — |
| Evening Standard | Sharpley, Anne | — |
| Evening News | Meyer, Caren | — |
| Sunday Express | Brittenden, Arthur | — |
| Sunday Observer | Dunn, Cyril | — |
| Sunday Graphic | — | Devon, Stanley |
| New York Times | Clarke | — |
| Christian Science Monitor | Sorenson, Miss Marian | — |
| Toronto Star of Canada | Johnston, A. Munroe | — |
| Rand Daily Mail (and other S.A. dailies) | Hughes A. B. | — |
| **Agencies** | | |
| Reuters | Batcelor, Ronald | — |
| Associated Press | Steinkopf. Alvin | Royale, Denis; Priest Leslie |
| Australian Consolidated Press | Matheson, Anne | — |
| Exchange Telegraph | Whicker, Alan | — |
| Agence France Presse | Wauthier. C.G.R. | — |
| **Magazines** | | |
| Life Magazine | Burker, Ronald | Mydans. Carl Meyer |
| Time Magazine | Hughes Ed. H. | — |
| Picture Post | — | McKeown (initials unknown) |
| Ashanti Times | Amah. Foli | — |
| Gold Coast Daily Graphic | Timothy, Bankole | — |
| **Photographic** | | |
| Magnum Photo Inc. (Paris & New York) | — | Brake, Brian |
| British Newsreel Associated Services Ltd. | — | Turner P. J. (Pathe) |
| Council of Photographic News Agencies | — | Case, Ronald (Keystone) Ludford, Herbert (Planet) |
| Reflex Pictorial Press Service | — | Varjas, George |
| Camera Press Ltd | — | Moore, David |
| **Radio & T. V.** | | |
| Independent T. V. News Ltd. | — | Grant Ian; Gray, Martin |
| B. B. C. Team | | |
| Talbot Godfrey, W. Rusell, Audrey (Miss) Thomas Wynford Vaughan Lycott, Eric Sarney, Harvey Fleming, Tionel D. Topping, Geoffrey | | MacKay Gordon; Rowley, G. E. |
| Gold Coast Broadcasting Service | Morris, Sampson | — |
| Columbia Broadcasting System. U.S.A. (TV) | Kendrick Alex | MacClure Wm Tsoonis, Kryn Reitberger Maurice. |
| De Franca Organisation (American TV) | — | Shirley, Millard |

Gbogbo awọn wọnyi ni yio ṣe afihan Nigeria fun gbogbo aiye. Nitorina, o ṣe e ṣe fun wa lehin igbati ọba ba tilọ tan ki a ni ifọkanbalẹ ati igbagbọ lori wipe gbogbo orilẹ ede ode agbaiye lo mọ pe orilẹ ede ola kan wa ti npe npe ni NIGERIA. Anfani eleyi ko kere e.



OLOYE AGUNLEJIKA KEJI, LỌJA OKEBODE

On jẹ ọkan ninu awọn agbẹ to mu ohun ifihan wa si ifihan iṣẹ agbẹ ti wọn ṣe laipe. On lo wa ngba ebun ju lọdọdun lati igbati wọn ti nṣe ifihan iṣẹ agbẹ na. On na pẹlu awọn to gba ẹbun lọdun yi.

## ESI ORO GABRAEL DADA

(Berẹ lati oju iwe 5)

...ko ha ni Gọngiran bi ni?

Njẹ iru iwa bẹ le ṣẹlẹ larin Ọba kan, Ọgbẹni Gabriel Dada? Ile li a ti nko ẹsọ lọ ode.

9. Awọn wo lo ko Hausa Tasafa si iwaju ile Oye awọn baba wa li ọjọ ti awọn Agba Ijẹṣa ati Ọba fi nfi Daddi Gureje Aṣọgbẹ jẹ oye awọn baba rẹ ni 29:6:52, ṣaju idaru igbana.

10. Bawo ni Gabriel Dada ti dagba to nigbati Daddi Gureje, Ologbe Riṣawẹ Adedeji ati Ẹbi wọn fi nfi Paun bo ile Oye na?

11. Kini idi rẹ ti awọn Alaṣẹ Afinljoya pẹlu Ọwa ṣe fi Daddi Gureje Aṣọgbẹ jẹ Oye Riṣawẹ ni 29:6:52?

12. Nibo ni orukọ wọnyi ti wa, Ijapa, Onija ati Ọgbọnran?

13. Njẹ oye miran mbẹ ni igboro Ilẹṣa ti o ju Oye Riṣawẹ lọ ti ko nṣe ti idile? Bi idahun ba jẹ bẹni, melo ni Aṣọgbẹ ti da ninu wọn ri?

14. Oye wo li a gbọ pe Daddi Gureje jẹ ṣaju ti o fi fẹ aya, ti o fi lowo to eyi ni, ti o si fi ni alaiki, tobẹ ti o fi jẹ pe ti a ba fi owo, alaiki, ọgbọn ibinibi, iwọntunwọnsi ninu ohun gbogbo rẹ we ti awọn apakeji, ti Daddi Gureje nikan tayọ sibẹsibẹ.

15. Ẹsun melo li a le kasi Daddi Gureje Aṣọgbe lọṣẹ? Igba melo li orukọ rẹ han ninu iwe Idajọ? Igba melo li o lọ ẹwọn ri yala nitori ole jija tabi ipaniẹ?

Lakotan, ko si ọrọ ibinujẹ larin idile Gureje Aṣọgbẹ—Awa ko mọ boya ọrọ ibinujẹ mbẹ lọdọ Gabriel Dada?

A ko bi Gọngiran ni Ilẹṣa Awọn ọmọ rẹ ti o bi ni Ilẹṣa li o bi awa ni ti awa. ...gbẹ Oye ko gbẹ wa. Ẹsọ li awa wa dabẹ.

Awa ko wa oye lati fi laya, tabi lati fi lowo. Oluwa ti ṣe owo ala ti awa yio na fun wa.

Lori gbigba ogun awọn Baba nla wa pada ni baba wa, Daddi Gureje Aṣọgbẹ fi na ọpọlọpọ owo. Ko fi ọmọ ọfẹ, bo li ara rẹ ko o; ko ta ile; bẹni ko ya owo pẹlu.

Awọn ti o ngowo ago ninu awọn aya ko pada wa gbe ti ata. Aṣọgbẹ ko ogbe owo oju, ko gba jọwọbamiṣe. Lọjajẹmọ li o njẹun, o nmu, nitori Oluwa ni alaṣẹbinu fun baba wa ati awa ọmọ rẹ pẹlu.

Bi o ba ṣe ti awọn olominran awọn iba ti lọ so bi bi Sango, Apiri nla ni eyi lati ọdọ Ọlọrun. Bi a ṣe nmọ Onwapọle re o. Ajulọ eyi ma de ga o.

A' dupẹ lọwọ Ọlọrun pe awa ko fi agidi fi ara wa joye. Awọn alaṣẹ Afinljoye li o fiwa jẹ. Lati kekere Ajanaku li Erin ti po ju Ẹfọn lọ. Ijọba ti ṣetan lati wadi odiọ lori ọrọ Ẹtọ wa.

Ọgbẹni Dada iba fi ẹnu bọ Ẹpo, iba fi ẹnu bọ Aṣẹ. Idile Aṣọgbẹ yio wọle lọla.

Nitori ki Ẹgbirọbi igba kọji ma ba bọ silẹ li a ṣe fi ara mọ ohun ti igba Oyinbo gbe de.

O digba kanna.

EZEKIEL GUREJE.

